63

# JOHANU KEJI

**(A.D. 90)**

ORI 1.

**Ìkíni.**

ALAGBA si ayanfẹ obinrin-ọlọ́lá ati awọn ọmọ rẹ̀, awọn ti mo fẹ ni otitọ; kii sii ṣe emi nikan, ṣugbọn gbogbo awọn ti ó mọ otitọ pẹlu; (3 Jhn 1; 1 Jhn 3:18; Jhn 8:32.)

2. Nitori otitọ ti ngbe inu wa, yoo si maa bá wa gbe títí. (2 Pet 1:12; 1 Jhn 1:12.)

3. Oore-ọfẹ, aanu, ati alaafia, yoo wà pẹlu wa, lati ọdọ Ọlọrun Baba, ati lati ọdọ Jesu Kristi, Ọmọ Bàbá, ninu otitọ ati ninu ìfẹ́. (1 Tim 1:2.)

**Ìmọ̀ràn ati ìkìlọ̀.**

4. Mo yọ̀ gidigidi pe mo ti rí ninu awọn ọmọ rẹ ti nrin ninu otitọ, ani bi awa ti gba ofin lati ọdọ Baba.

5. Njẹ nisinsinyìí mo bẹ̀ ọ́, obinrin-ọlọ́lá, ki i ṣe bi ẹni pe emi nkọwe ofin titun kan si ọ, bikoṣe eyi ti awa ti ní ní àtètèkọ́ṣe, pe ki awa fẹ́ràn ara wa. (1 Jhn 2:7; 3:11.)

6. Eyi si ni ìfẹ́, pé, ki awa maa rìn nipa ofin rẹ̀, Eyi ni ofin naa, ani bi ẹ ti gbọ́ ni àtètèkọ́ṣe, pé, ki ẹyin maa rìn ninu rẹ̀. (1 Jhn 2:5; 2:24.)

7. Nitori ẹlẹ́tàn pupọ ti jade wa sinu ayé, awọn ti kò jẹ́wọ́ pe Jesu Kristi wá ninu ara. Èyí ni ẹlẹ̀tàn ati Aṣòdì sí Kristi. (1 Jhn 4:1–3; 2:22.)

8. Ẹ kíyèsára yin, kí ẹ má sọ iṣẹ́ ti awa ti ṣe nù, ṣugbọn ki ẹyin ri èrè kikun gbà. (Mk 13:9; 1 Kor 3:8; Heb 10:32.)

9. Olukuluku ẹni ti o ba nrú ofin ti kò si duro ninu ẹ̀kọ́ Kristi, kò gba Ọlọrun. Ẹni ti o ba duro ninu ẹkọ́, oun ni o gba ati Baba ati Ọmọ. (1 Jhn 2:23.)

10. Bi ẹnikẹni ba tọ̀ yin wá, ti kò si mu ẹkọ́ yìí wá, ẹ má ṣe gba a si ilé, ki ẹ má sì ṣe ki i. (Rom 16:17.)

11. Nitori ẹni ti o ba ki i, o ni ọwọ́ ninu iṣẹ́ buburu rẹ̀. (1 Tim 5:22,12.)

**Ọ̀rọ̀ Asọpari.**

12. Bi mo ti ni ohun pupọ lati kọwé si yin, emi kò fẹ lo ìwé-ìkọ̀wé ati jẹlú-ikọ̀wé. Ṣugbọn emi ní ireti lati tọ̀ yin wá ati lati ba yin sọ̀rọ̀ lójúkojú, ki ayọ̀ yin baa lè kún (3 Jhn 13,14; 1 Jhn 1:4.)

13. Awọn ọmọ arabinrin rẹ àyànfẹ́ ki ọ.

64

# JOHANU KẸTA.

**(A.D. 90)**

ORI. 1.

**Ìkíni.**

ALÀGBÀ si Gaiusi olufẹ, ẹni ti mo fẹ́ ninu otitọ. (2 Jhn 1.)

2. Olufẹ, emi ngbadura pe ninu ohun gbogbo ki ó lè maa dara fun ọ, ki o sì maa wà ni ìlera, ani bi o ti dara fun ọkàn rẹ.

3. Nitori mo yọ̀ gidigidi, nigba ti awọn arakunrin dé ti wọn si jẹri si otitọ igbe-ayé rẹ, ani bi iwọ ti nrin ninu otitọ (2 Jhn 4; ẹsẹ 5,10.)

4. Emi ko ni ayọ̀ ti o pọju eyi lọ, lati maa gbọ́ pe, awọn ọmọ mi nrìn ninu otitọ. (1 Kor 4:15; Film 10.)

**Ọ̀rọ̀ Ìyànjú fun Gaiusi.**

5. Olufẹ, iwọ nṣe iṣẹ́ igbagbọ ni ohunkohun ti o ba nṣe fun awọn ará,

ati paapaa fun àlejò. (Rom 12:13; Heb 13:2.)
6. Ti wọn njẹ̀rìí si ìfẹ̀ rẹ niwaju ijọ: ìwọ yoo si ṣe rere bi iwọ bá sín wọn siwaju lọ̀na ìrin-àjò wọn gẹgẹ bi o ti yẹ ninu Ọlọrun. (A.A. 15:3; Tit 3:13.)
7. Nitori pe nitori orukọ rẹ̀ ni wọn ṣe jade lọ, laigba ohunkohun lọwọ awọn Keferi. (A.A. 5:41; 20:33,35.)
8. Nitori naa o yẹ ki a gba irú awọn wọnyìí, ki awa lè jẹ́ alabaṣiṣẹ pọ̀ pẹlu otitọ.

**Ìbáwí fun Diotrefe.**

9. Emi kọwe si ijọ: ṣugbọn Diorefe, ẹni ti o fẹ́ lati jẹ olori laarin wọn, kò gbà wá. (2 Jhn 9.)
10. Nitori naa bi mo bá dé, emi o mu iṣẹ rẹ̀ ti o ṣe wá si iranti, ti o nsọ ọ̀rọ buburu ati isọkusọ sí wa: eyiyìí ko si tẹ ẹ lọrun, sibẹ oun tikararẹ kọ̀ lati gbà awọn ará, awọn ti o si nfẹ gbà wọn, o ndá wọn lẹ́kun, o si nle wọn kuro ninu ijọ. (2 Jhn 12; ẹsẹ 5; Jhn 9:34.)

**Ìyìn fun Demetriu.**

11. Olufẹ máṣe ṣe afarawe ohun ti i ṣe ibi, bikoṣe ohun ti i ṣe rere. Ẹni ti ó bá nṣe rere ti Ọlọrun ni: ẹni ti o ba nṣe buburu ko ri Ọlọrun. (Psm 37:27; 1 Jhn 2:29; 3:6,9.)
12. Demetriu ní ẹrí rere lọdọ gbogbo eniyan ati ní ti otitọ tikararẹ pẹlu: nitootọ, awa pẹlu si gba ẹ̀rí rẹ̀ jẹ́; ẹyin si mọ pe ẹrí wa otitọ ni. (1 Tim 3:7; Jhn 21:24.)

**Ọ̀rọ̀ Àsọ́parí.**

13. Emi ní ohun pupọ lati kọ̀wé si ọ, ṣugbọn emi kò fẹ́ fi jẹlú-ìkọ̀wé ati gègé kọ wọ́n. (2 Jhn 12.)
14. Ṣugbọn mo ni ìrètí lati ri ọ láìpẹ́, a o si sọ̀rọ̀ lójúkojú.
15. Alaafia fun ọ, Awọn ọ̀rẹ́ ki ọ! Ki awọn ọ̀rẹ́ ni orukọ-orukọ! (1 Pet 5:14.)

65

# JUDA

**(A.D. 66)**

ORI 1.

**Ọ̀rọ̀ iṣaaju.**

JÚDA, iransẹ Jesu Kristi, ati arakunrin Jemisi, si awọn ti a pè, olufẹ ninu Ọlọrun Baba, ti a si pamọ fun Jesu Kristi: (A.A. 1:13; 1 Pet 1:5.)
2. Ki aanu, ati alaafia, ati ìfẹ́ maa bí si i fun yin. (1 Pet 1:2; 2 Pet 1:2.)
3. Olufẹ, bí mo ti nlàkàkà pupọ lati kọ̀wé si yin niti ìgbàlà ti i ṣe ti gbogbo eniyan, nkò gbọ́dọ̀ ṣàìmá kọ̀wé si yin, ki nsì gbà yin niyanju lati maa jà gidi-gidi fun igbagbọ, ti a ti fi lé awọn eniyan-mimọ lọ́wọ́ lẹẹkanṣoṣo. (Tit 1:4; 1 Tim 6:12.)
4. Nitori awọn eniyan kan nbẹ ti wọn nyọ́ wọle, awọn ẹni ti a ti yàn lati igba àtíjọ́ si ẹ̀bi yìí, awọn alaiwa-bi-Ọlọrun, ti nyi oore-ọfẹ Ọlọrun wa padà si wọbia, ti wọn si nsẹ́ Oluwa kanṣoṣo naa, ani Jesu Kristi Oluwa wa. (Gal 2:4; 2 Pet 2:1; Rom 9:22.)

**Ìwà ati iparun awọn olukọ èké.**

5. Njẹ emi nfẹ lati rán yin leti bi ẹyin tilẹ̀ ti mọ̀ gbogbo rẹ̀ lẹẹkan ri, pe Oluwa, nigba ti o ti gba awọn eniyan kan là lati ilẹ Egipti wá, lẹhin naa o run awọn ti kò gbagbọ. (Num 14:29; Psm 106:26.)
6. Ati awọn angẹli ti kò tọ́jú ipò ọlá wọn, ṣugbọn ti wọn fi ipò wọn silẹ̀, awọn ni o ti fi pamọ ninu ẹ̀wọ̀n aini-pẹkun nisalẹ̀ okunkùn de idajọ ọjọ nla. (Jhn 8:44; 2 Pet 2:4; Ifh 20:10.)
7. Ani bi Sodomu ati Gomora, ati awọn ilu àgbègbè wọn, ti fi ara wọn fun àgbèrè ṣíṣe bakan naa, ti wọn si ntẹ̀lé ara àjèjì lẹhin, awọn ni a fi lelẹ̀